# REBEKA, APẸẸRẸ IYAWO KRISTI

**Gẹnẹsisi 24:34-67**

**ẸKỌ 13 --- FUN AWỌN ỌDỌ**

**AKỌSORI: "Igbeyawo Ọdọ-Agutan de, aya rẹ̀ si ti mura tan" (Ifihan 19:7).**

**Ni Ile Rebeka**

Ninu ẹkọ ti a ṣe kọja, a kọ pe iranṣẹ Abrahamu, Elieseri, ti lọ si ilẹ Mesopotamia lati mú ọdọmọbinrin kan pada ti yoo ṣe iyawo fun Isaaki, ọmọkunrin Abrahamu. Bi o ti de ibi ti o n lọ, ni gẹrẹ lẹyin ilu ni ẹba kanga ni iranṣẹ naa ti pade Rebeka. Ko pẹ lẹyin naa arakunrin rẹ̀ naa wá si ibi kanga naa o si rọ awọn arinrin-ajo naa wá sinu ile wọn.

Wọn ko fi ohun kan silẹ lai ṣe lati mu irọrun bá awọn alejo wọnyii ti o ti ọna jijin wá. Wọn wẹ ẹsẹ wọn, wọn si gbé ounjẹ wá fun wọn. Ṣugbọn Elieseri kò i ti i sọ ohun ti o ba wa, eyi ti o ju ounjẹ lọ fun un. "Emi ki yio jẹun titi emi o fi jiṣẹ mi tán," ni ohun ti o wí. Nitori naa o sọ nipa oluwa rẹ̀, Abrahamu, ati ọrọ̀ nla ti o ní; ati nipa Isaaki ẹni ti yoo jogun nnkan wọnyii.

**Wọn Gbà Fun Un**

Nigba naa ni o sọ eredi irin-ajo rẹ̀, ti adura ti o gbà lẹba kanga, ati idahun si adura rẹ̀. Ṣugbọn o ṣe danindanin fun awọn ara ile Rebeka lati fi ohun si i. Wọn mọ̀ lẹsẹkẹsẹ pe lati ọdọ Oluwa ni ọran yii, wọn si wi fun Elieseri pe, "Mu u, ki o si ma lọ, ki on ki o si ma ṣe aya ọmọ oluwa rẹ, bi OLUWA ti wi." Pẹlu ẹkunrẹrẹ ayọ̀, ọmọ-ọdọ naa wólẹ̀, o si sin Oluwa. Nisisiyii o wá mọ̀ pe Oluwa ti ṣe ọna oun ni rere. O mu ọpọ ọ̀ṣọ́ fadaka ati wura, ati aṣọ jade fun Rebeka. O si fi ẹ̀bun fun iya ati arakunrin rẹ̀ pẹlu.

**Ifẹ Rebeka**

Ni owurọ ọjọ keji, Elieseri fẹ maa ba ọna rẹ̀ lọ ki o si mu Rebeka lọ, ṣugbọn iya ati arakunrin rẹ̀ beere pe ki o bá awọn joko "ni ijọ́ melokan, bi ijọ́ mẹwa, lẹhin eyini ni ki o ma wa lọ." Ṣugbọn iranṣẹ naa mọ̀ pe idaduro naa le mú ki atilọ tilẹ ṣoro si i, èsi rẹ̀ si ni pe, "Ẹ máṣe da mi duro, OLUWA sa ti ṣe ọ̀na mi ni rere, ẹ rán mi, ki emi ki o le tọ̀ oluwa mi lọ." Iya Rebeka pe e o si wi pe, "Iwọ o bá ọkunrin yi lọ?" O ni lati yàn funra rẹ̀; lai si iduro rara o wi pe, "Emi o lọ."

Lai tun fi ẹsẹ palẹ̀ siwaju, awọn ara ile Rebeka sure fun un, wọn si ran an lọ ni ọna rẹ̀ pẹlu Elieseri ati awọn ọkunrin rẹ̀, si ilẹ Kenaani lati ṣe iyawo Isaaki, ọmọ ileri fun Abrahamu.

**Ṣiṣe Iyawo ni Ọṣọ**

Oruka wura, jufù, iṣura iyebiye, ati aṣọ daradara ti a fi fun Rebeka ki o to pade Isaaki, lapapọ jẹ apejuwe awọn ẹbun ti ẹmi ti a n fi fun ọkàn ti o n làkàkà fun oore-ọfẹ Ọlọrun si i. Ifororoyan Ẹmi ti n kán sori ọkàn bi iri Ọrun, jẹ ara ọṣọ Iyawo Kristi pẹlu. Awọn ni ọṣọ iyebiye ti Ọlọrun n fi fun ni, ko si si ohun ti n fun ọkàn lẹwa bi Ẹmi Ọlọrun. Iri oju paapaa a maa tan ogo ti n wọ inu ọkàn ti a ti gbala, ti a ti sọ di mimọ́, ti o si ti tẹ siwaju titi Ọlọrun fi tú Agbara Ẹmi Mimọ́ nla nla jade.

**Ipe Lonii**

Ta ni yoo sọ, pẹlu ipinnu, igboya, ati igbagbọ́, bi Rebeka ti sọ pe: "Emi o lọ"? Ẹmi n sọ pe, "Ẹ máṣe da mi duro," fun awọn wọnni ti wọn n fẹ lati fà sẹyin, tabi ti wọn n fẹ mu awọn ẹlomiran fa ifi-ara-rubọ wọn kuro lọdọ Rẹ̀. Iwọ yoo ha wọ ibi ikọ̀kọ̀ Ọga-Ogo? Iwọ ha fẹ ki a fi iṣura Ọmọ Ọlọrun hàn fun ọ bi? Iwọ yoo ha wi pe, "Emi n fẹ awọn ọṣọ ti yoo mu mi ṣetan lati jẹ́ Iyawo Kristi?"

A ha le gbà ki a ma wa ni imurasilẹ? A ha le gba lati wi pe, "Oun yoo duro ni ijọ mẹwaa," tabi "Oun yoo duro ni ijọ marun-un," tabi "Oun yoo duro ni ijọ kan?" Rara o! A ni lati wi, nigba ti Ẹmi n rọ ni, pe, "Emi o lọ, emi o lọ." Ẹni ti o wà ni tosi ọdọ rẹ le wi pe, "Ni ọ̀la," ṣugbọn Ẹmi n wi pe "Lonii!" Ipe ti jade lọ. Awọn miiran ti wọn ti ri igbala ko ti i ri isọdimimọ; awọn miiran ko i ti gba agbara lati Oke wá, Agbara Ẹmi Mimọ nla nla. Iwọ yoo ha ṣafẹri ki o si gba awọn iriri ẹmi wọnyii, ati nipa bẹẹ ki o le wi pe "Emi o lọ"?

**Aya Isaaki**

Jẹ ki a fi awọn ibakasiẹ ti n gbe iyawo afẹsọna naa ati olutọ́ rẹ̀ lọ si ilẹ Kenaani silẹ, ki a si lọ siwaju. Nibẹ, bi aṣaalẹ ti n lẹ ba wa, a ri Isaaki lode lori pápá o n ṣe aṣaro, oun nikan. O gbé oju rẹ̀ soke o si ri awọn ibakasiẹ n bọ̀ wá lokeere. Diẹdiẹ wọn n sunmọ́ tosi. Nigba ti o ṣe o ri Rebeka bi o ti n sọkalẹ lori ibakasiẹ.

A sọ pe titi di oni-oloni ni ilẹ miiran nigba ti omidan ti o wà lori ibakasiẹ ba pade ọkunrin, o jẹ iwa ibuyin-fun ni, lati sọkalẹ. Rebeka ti beere ẹni ti ọkunrin ti o n rin bọ̀ ni oko i ṣe; nigba ti a si sọ fun un pe Isaaki ni, o fi ọ̀wọ̀ ati itẹriba bo ara rẹ̀ pẹlu iboju rẹ̀ -- eyi ti o jẹ pataki ninu aṣọ obinrin ni ọjọ wọnni. Ẹyin-oju nikan ni o gbọdọ hàn.

Loju kan naa Elieseri royin fun Isaaki ohun gbogbo ti oun ti ṣe. Inu Isaaki ti dun to lati mọ pe Oluwa ti ṣe ọna iranṣẹ naa ni rere! Pẹlu ọ̀wọ̀ o mu Rebeka wá si inu agọ́ ti Sara, iya rẹ̀, ti n gbe. Rebeka di aya Isaaki, o si fẹran rẹ̀. O le sọ nipa rẹ̀ pe, "Iwọ li ẹwà gbogbo, olufẹ mi; kò si abawọ́n lara rẹ" (Orin Sọlomọni 4:7).

**Awọn Ohun Amuyẹ ti Iyawo ni lati Ni**

Rebeka ni iwa ti a n fẹ lọna gbogbo: o ni ifẹ, itẹriba, aapọn, agbara, ọyaya, ilawọ, o si n ṣe "alejò laisi ikùn sinu" (1 Peteru 4:9). O fi ile rẹ̀ silẹ lọ i pade ọkọ rẹ̀ ni ilu okeere. Isaaki jade lati wá mu un. Jesu yoo fi itẹ Rẹ̀ silẹ ni Ọrun lọjọ kan lai pẹ yii Oun yoo si sọkalẹ lati wá mu Iyawo Rẹ̀ ti n reti Rẹ̀. Iwọ ha ṣetan?

## AWỌN IBEERE

1 Ki ni ṣe ti ara fi n yá iranṣẹ naa to bẹẹ lati pada lẹsẹkẹsẹ pẹlu Rebeka?

2 Ki ni iriri ti o ni lati fi hàn pe Oluwa ti dahun adura rẹ̀?

3 Ibeere wo ni a bi Rebeka? Ki si ni idahun rẹ̀?

4 Lọna wo ni Rebeka fi jẹ apẹẹrẹ Iyawo Kristi?

5 Awọn wo ni yoo jẹ Iyawo Kristi?

6 Ta ni kọ́ ri awọn ibakasiẹ ti n bọ̀?

7 Royin nipa ipade Isaaki ati Rebeka.

8 Darukọ ninu awọn àmi ti n tọka si isunmọtosi bibọ̀ Oluwa.